Bibeli fun awon omode



# Orun, Ile Olorun didara

Ikosile gba owo: Edward Hughes

Ayaworan: Lazarus

Olu'lo: Sarah S.

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2013 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi, niwon igba ti o ko so di owo.

Nigbati Jesu gbe nile aiye o so nipa orun fun awon omo ehin re. o wipe “Ile BABA mi”, o wipe opolopo ibugbe nla lowa nibe.



Ibugbe nla elewa. Orun tobi o si lewa ju ilekile li aiye lo.



Jesu wipe, "Mo nlo lati pese aye sile fun yin. Bi emi balo pese aye sile fun yin, Emi yio pada wa lati gba yin sodo mi".



Jesu losi orun, lehin ti ojinde ni isa oku. Nigbati awon omo lehin re na wo, agba Jesu losi oke, ofurufu si gba kuro loju won.



Lati igba na, Awon Kristeni ti ranti ileri Jesu latipadawa mu wa. Jesu so wipe ohun yio pada de lojiji, nigbati ako reti.



Sugbon bawo li awon ti oku ki Jesu t'ode? Bibeli wipe won losi orun lati wa pelu Jesu. Lati ma wa ninu ara je wipe awa pelu Oluwa.



Ifihan, Iwe to kehin ninu Bibeli, so fun wa bi orun se dara to. Ohun to yani lenu ni wipe, li ona to dara, orun ibugbe olorun. Olorun wa nibi gbogbo, sugbon orun li ite e re.



Awon angeli awon awon eda alaye miiran nsin Olorun l'orun.  Beni awon omo Olorun ti oti ku ti won sit i losi orun.
Won nko orin iyin si Olorun.



Eyi li okan ninu awon orin ti won nko:



IWO L'OGO YE, NITORI OTI RA WA PADA FUN OLORUN NIPA EJE RE LATI INU GBOGBO EDE ATI ORILE-EDE O ...



... SI FI WA SE OBA ATI ALUFA SI OLORUN WA.
(Iwe Ifihan ori karun ese kesan)



Iwe to kehin ninu Bibeli fi han wipe orun li “Jerusalemu titun“. Otobi pupo, pelu ogiri titobi lode. Ogiri ilu na je jasipa, ti o mo daradara.



Awon okuta meremere li afi ko ogiri ilu na, ti o ntan pelu alarabara. Enu ona Kankan ti o wo ilu na li afi

pealii (okuta olowo iyebiye) se.





Awon enu ona peali yi ako nti won rara. Ejeki awole ki ase abewo re … AAA!



Orun lewa ninu.  Afi fadaka ko ilu na, bi awo jiji.  Awon adugbo re li afi fadaka se.



Elewa, omi ti o mo iye nsan lati inu ite Olorun.  Leti odo na  mejeji li agbin igi iye si, ti akoko ri ninu ogba Edeni.



Awon igi yi yato. O so orisi eso mejila, orisi eso kan li osu kan. Ewe igi iye wa fun iwosan awon orileede.



Orun ko fe orun tabi osupa fun imole. Ogo Olorun fun ara re kun fun imole iyanu. Kosi oru nibe.



Awon eranko orun yato. Won je ohun ti ale fi sere. Ikoko ati eran agbo nje koriko papo. Awon kiniun nla nje koriko bi esin. OLUWA wipe, "won koni farapa tabi parun li gbogbo oke mi".



Bi ase wo yika, ari wipe a o ri awon ohun kan li orun. A o gbo oro ibinu. Enikeni ko ja tabi se ahun.



Ako fi kokoro si enu ilekun nitori wipe kosi ole li orun. Kosi iro, apaniyan, eke, tabi awon eni ibi. Kosi ese kan li orun.





Li orun pelu Olorun kosi ekun mo. Nigba miiran awon eni Olorun nsonkun li aye nitori aye yi. Li orun Olorun yio nu gbogbo omije wa nu.

kosi iku li orun rara. Awon eni Olorun yio wa pelu Oluwa titi lai. Kosi Ikoro mo,
kosi ekun
mo, kosi
irora mo.



Kosi aisan mo, kosi iyapa mo, kosi isinku mo.  Gbogbo eniyan li orun nyo pelu Olorun.



Parpari re, Orun wa fun awon omodekunrin ati awon omodebinrin.



Li orun iwe kan nbe ti anpe li iwe iye odo agutan. O kun fun oruko awon eniyan. Nje o mo oruko awon towa nibe bi? Awon ti o gbekele Jesu. Se oruko o re wa nibe?



Oro igbehin Bibeli je oro ipeni. “Ati Emi ati Iyawo wi pe, ‘Wa!’ Jeki eniti o gbo so wipe ‘Wa!’



Jeki eniti ongbe ngbe wa. Ati eniti o fe, jeki omu omi iye l'ofe."



Orun, Ile Olorun didara

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Johannu 14; Iwe Korinti keji ori karun;
Iwe Ifihan ori 4, 21, 22

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi 119:130

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe
otito ni eyi, so fun Olorun wipe:
Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun
soro lojumo!
Johannu ori keta ese kerindinlogun.